# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Idabun Si Ibere Prophet Isaac Adeyemo

(1)

Oloto, Isu mi yio dun bi e ba le gba mi laye lati dahun ibere Isaac Adeyemo, Ikirun ti o jade ninu Iwe Irohin Yoruba ni ojo keta osu keta odun yi,

1. Awon omo ti Maria tun bi lehin igbati o bi Jesu tan niyi :— Jakobu, Juda, Jose ati Simoni, wo Marku ori kefa ese keta.

2. Oruko awon amoye ti o wa ki Jesu nigbati a bi I ni:-

1. Gasper lati Egypt ti o fun ni wura. (2) Ekikeji ni Melchoir lati Arabia ti o fun un ni turari.

(3) Eniketa ni Balthasar lati Babeli ti o fun un ni Ojia.

Ki a kiyesi pe a w o n amoye owonyi wa lati Ila-Orun gegebi Bibeli ti wi,

Mo dupe fun aye ti e gba mi, Iwaju ni e o ma te si o,

Emi ni
Isaac Adeyemo
OGBOMOSO

(2)

Si ibere Ogbeni Isaac Adeyemo Ikirun ti o here ninu Iwe Irohin Yoruba 3/3/52 gegebi imoye mi Awon omo ti Maria bi lehin ti o bi Jesu Kristi Oluwa tan ni iwonyi :— (1) Jakobu, (2) Jose. (3) ati Juda Matteu 13: ese 55 Marku 6: ese 3 Marku 16 ese 1 nwon tun je awon omo iya Oluwa ni Arakunrin nibi wonyi Marku 3: 3 Luku 8 ese 19—20 Joha 2 ese 12 John 7 ese 3—5 Galatia 1 ese 19, Juda 1 ese 1

(2) Oruko awon amoye meta na ni yi:- (1) Gaspar (2) Melchior (3) Baltasar: sugbon a ko da oruko won sinu Bibeli ti Yoruba bi ko se awon amoye ti won ti Ila Orun wa si Jerusalem awon foribale fun omo owo na awon si tan lore, Ore na ti awon ta Jesu si ni (1) Wura (2) Turari (3) ati Ojia, Sugbon a ko so oruko eni so fi iru ebun kokan yi fun un a sa gbo pe awon meta fi okan olowo yebiye meta yi ta Jesu Kristi Oluwa ati Olugbala araiye lore ni o, A ko so Oruko ila won fun wa ninu Bibeli ti Yoruba bikose awon ti Ila orun wa.

Olotu owo re yio ma roke, oko oba ko ni pa nyin lese o, amin ase.

Emi ni,
D. Babalola Owa
ERUKU Lona ILORIN

(3)

Olotu, Ni idahun si ibere Prophet Isaac Adeyemo ti Ikirun ti o jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti ojo keta osu keta odun yi.

1. Oruko awon omo ti Maria Iya Jesu tun bi lehin igbati o ti bi Jesu Kristi Oluwa wa tan ni, Jakobu, Jose, Juda ati Simoni pelu awon omobirin ti Bibeli ko da oruko won. A le ri i ka ninu Iwe Marku ori kefa ese keta.

2. Oruko awon amoye meta ti o wa ki Oluwa wa Jesu Kristi nigbati a bi I ni, Gaspar, Melchoir, ati Balthasar, N i p a ara ilu ti nwon se, a gba wipe lati Babeli ni okan ti wa nitoripe ni Babeli ni a gburo awon amoye ni akoko na, Wo iwe Jeremiah ori kokandinlogoji, ese keta fun oruko awon amoye die to wa ni Babeli lakoko na.

A tun so w i p e okan ti ilu Parsia wa (Ise Aposteli 2:9) nitoriwipe olori Orise won ni ile Parsia ni a k o k o na ni imo tabi oye (magianism).

Enikeja awon a m o y e wonyi lo ti apa ila orun Kaldea wa ni a gba wipe awon kun fun ogbon ati oye ni a k o k o na Wo Daniel ori keji. ese keji titi de ikarun iwo yio ka nipa awon amoye ati ologbon ara Kaldea.

Ki o ye olukuluku wa wipe otito ni ilu ti awon amoye wonyi ti jade, Nwon p a d e ni oju ona ni. Nigbati ohun ti nwon nlo fun je okanna ni n w o n ba pa irin po.

Ebun ti enikokan won si fi fa Olugbala gbogbo eda lore ni Wura, Turari ati Ojia l e h i n igbati nwon ti wole ti nwon si ti foribale fun un tan, Wo Matteu ori keji ese kokanla.

Mo dupe o, Olotu fun aye ti e gba mi. Iwaju ni opa ebiti gbo gbo wa yio ma a re si o.

Emi ni,
M. O, Oyarinde
Box 30
OGBOMOSHO

### ALICE JOKOTADE KI LO FA A?

Alagba, O ya wa lenu lati ri i ka ninu Iwe Irohin Yoruba ti ojo kedogbon osu keji odun yi pe lowo Omidan Alice Jokotade ni o ku si nipa a ti te aworan re jade ninu Iwe Irohin Yoruba. Mo fe la a ye Omidan Alice Jokotade po, riri ti a nfe ri aworan re ninu iwe ki ise pe a fe lo o fun ohun kan ti o yato.

Ohun pataki ti a fe titori re ri I ni ti awon alaye re gbogbo ti o mu eko dani nitori aka-tunka ni mo ma a fi alaye re se, awon oniti o jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti ojo 1/1/51 ; 19/2/51; 11/6/51; 10/9/51; 24/12/51; 31/12/51 ati ti 21/1/52,

Gege bi a ti ri ti awon Ogbeni Samuel I d o w u Ajibiorere ati Evengelist Joseph Akande ninu Iwe Irohin ti 22/2/51 ati ti 16/7/51. Be na ni a si nfe ri ti Omidan Alice Jokotade paapa.

Ohun ti o fa a ti a fi fe ri I niyi nitoripe bi egun eni ba njo daradara ori a ma a si atokun. Mo si dupe lowo awon ti o ko de imora na siwaju mi. A fe ki Olotu ati Ogbeni Idowu Ajibiorere-lofe ba wa ba arabinrin na soro ki foto re o jade ninu Iwe Irohin Yoruba a ko-ni-leko yi.

Emi ni
Josiah Ogundipe
Abeokuta


## AMODI IMU TI LO



MENTHOLATUM



Ki amodi imu ba le tete lo, lo "Mentholatum" Pelu iyanu ni egbogi fifi-si-imu yi. fi tete oyara sise. Sekese ti o ba ti loo ni wa ti ri i pe pelu irorun ni gbogbo idoti imu o ti bere si jade lesekese, Oorun "Mentholatum" a tete fun e ni aye a ti ma a mi dada. Ki o si tun fi pa ofun ati aiya fere. Eyi na a si tun ma ne mu ki gbogbo iwojepo aller lo kiakia- Tete lo ra ide tabi ogolo "Mentholatum" kan loni.

Bere fun Mentholatum gan an Eyiti o je pe awon Mentholatum Co. Ltd., (Est. 1889) Slough, England nikan ni nwon nse e.

## Pataki Oja Ti Awon Onisowo Le Ri Ere Je Pupo Lori Re Niyi

Reids Watney Stout
Reids Watney Stout
Reids Watney Stout

E tete wa ra egbogi wonyi—

Ogun Oju (Eye Drops), Ogun Akokoro (Toothache Drops), Ogun Eti (Earache Drops) Ogun Ike (Fever Cough Mixtures), Ogun Igbe-gburu, (Diarrhoea Mixtures), Orisirisi Ogun Atejese (Tonics of different kinds), Olive Oil, Extract of Malt, ati Cod Liver Oil,

E tete wa ra oti Stout-beer ati ogun orisirisi ti o dara ju ti a si nta ni edinwo yi lodo—

**Messrs J. A. Ajao Brothers.**
10, & 7, Egerton Road, Lagos, Nigeria.

E MA KA IWE Irohin Yoruba NIGBAGBOGBO

